# IMỌRAN PAULU FUN AWỌN ARA FILIPPI

## Filippi 1:1-7, 27-30; 2:1-30

## ẸKỌ 405 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ẹ máṣe fi ija, tabi ogo asan ṣe ohunkohun: ṣugbọn ni irẹlẹ ọkàn ki olukuluku ro awọn ẹlomiran si ẹniti o san ju on tikararẹ lọ" (Filippi 2:3).**

**I Ọrọ Ifẹ**

1 Paulu bá awọn ti o gbagbọ́ ni Filippi sọ̀rọ o si dupẹ fun irẹpọ wọn, Filippi 1:1-5

2 O ni igbẹkẹle pe iṣẹ Kristi yoo maa gbèru siwaju laaarin wọn, Filippi 1:6, 7

**II Iṣileti Fun Iduroṣinṣin**

1 O gbà wọn niyanju lati gbé igbesi-ayé Onigbagbọ́ ti o ṣe deedee, Filippi 1:27; 1 Timoteu 4:12

2 Igbesi-ayé ti awọn Onigbagbọ́ n gbé jẹ ayọ̀ wọn, ki i ṣe inira gẹgẹ bi awọn ọ̀tá wọn ti le rò ó si, Filippi 1:28-30

**III Ifẹ, Iṣọkan ati Irẹlẹ**

1 Ayọ ọkàn Paulu ni pe awọn Onigbagbọ́ wọnyii n gbé ni irẹpọ ati iṣọkan, Filippi 2:1-4; Efesu 4:1-3

2 Wọn gbọdọ ni iru èro ti Kristi ninu wọn ki wọn si rìn ni irẹ̀lẹ gẹgẹ bi Kristi ti ṣe, Filippi 2:5-8

3 Nitori irẹ̀lẹ ati igbọran, Ọlọrun ti gbé Kristi ga, Oun yoo si mu ki gbogbo eniyan maa sin In fun ogo Ọlọrun Baba, Filippi 2:9-11

**IV Awọn Onigbagbọ́ ti o Gbọran Wà Gẹgẹ bi Imọlẹ**

Ọlọrun n mu ifẹ ati eto igbala Rẹ̀ ṣẹ ninu awọn Onigbagbọ́ ti o ṣe oloootọ ti o si gbọran, Filippi 2:12, 13

Igbesi-aye Onigbagbọ́ jẹ ẹri ti n tan imọlẹ ninu okunkun ayé, Filippi 2:14-18; Efesu 5:8; 1 Tẹssalonika 5:5

**V Awọn Iranṣẹ**

1 Timoteu ṣe oloootọ ṣugbọn awọn ẹlomiran n wá ohun ti ara wọn, Filippi 2:19-24; 2:4; 1 Kọrinti 10:24

2 Epafroditu, oloootọ omọ-ogun, ṣaisàn ṣugbọn Ọlọrun da a si, Filippi 2:25-28

3 O yẹ lati fi ayọ gbà a gẹgẹ bi ẹni ti o ti fi ohun gbogbo jì nitori ti Kristi, Filippi 2:29, 30

**ALAYE**

Aniyan ọkàn Paulu ati ọrọ iyànjú rẹ̀ si ijọ Filippi jade lati inu ọkàn rẹ̀ gẹgẹ bi baba si awọn ọmọ rẹ̀. Ijọ yii bẹrẹ pẹlu iyipada ọkàn Lidia oniṣowo aṣọ elese aluko. Ni ojuran ni oru Paulu ri ọkunrin ara Makedonia kan ti o wi pe, "Rekọja wá si Makedonia, ki o si ran wa lọwọ." O gbagbọ́ pe lati ọdọ Oluwa ni iran yii ti wá, ni ẹsẹkẹsẹ o fi Troasi silẹ lati lọ si Makedonia nibi ti Lidia jẹ́ eniyan kin-in-ni ni ilu Europe ti o yipada di Onigbagbọ́, eyi si jẹ́ ibẹrẹ ijọ nibẹ (Iṣe Awọn Apọsteli 16:9-15). Laipẹ jọjọ, ọdọmọbinrin kan ti o ni ẹmi afọṣẹ ri iwosan o si yi pada, bakan naa ni ọgbẹni onitubu ati ẹbi rẹ̀. Laiṣe iyemeji awọn eniyan diẹ wọnyii ni wọn jẹ ipilẹ agbo awọn Onigbagbọ́. A kọ Episteli yii lati Romu nigba ti Paulu wà ninu tubu nibẹ.

**Ikini**

Paulu ki awọn eniyan mimọ́ ti o wà ni Filippi, bakan naa ni o ki awọn biṣọpu, ati awọn diakoni, eyi si fi hàn pe ohun gbogbo n lọ letoleto ninu ijọ naa ati pe ijọ naa n gberu. Nigbakuugba ti ọkàn rẹ̀ ba ti rò nipa wọn ni o maa n kun fun ayọ̀ ni ti iṣẹ ti Ọlọrun ti ṣe laaarin wọn. O ni idaniloju pe Ọlọrun yoo pari iṣẹ ti o ti bẹrẹ. Adura rẹ̀ pẹlu le jẹ adura ọpẹ ati iyin nitori irẹpọ ti o ni pẹlu awọn eniyan mimọ́ ti o wà ni Filippi. Irẹpọ tootọ ninu Ihinrere ki i ṣe lori pe awọn eniyan wà ni ibi kan naa ni igba kan naa, ṣugbọn ibarẹ nipa ti ẹmi ni. Awọn eniyan ti wọn ba wà ni iṣọkan pẹlu Ọlọrun ti wọn si n gbọran si Ọrọ Rẹ̀ yoo ni irẹpọ pẹlu Ọlọrun ati awọn eniyan Ọlọrun.

**Iduroṣinṣin**

Imọran Paulu si awọn Onigbagbọ́ ti o wà ni Filippi ni pe ki ọ̀rọ sisọ wọn tabi iwa wọn jẹ eyi ti yoo mu iyin ba Ihinrere Kristi. O mọ dajudaju pe awọn eniyan miiran yoo jẹwọ pe Onigbagbọ́ ni awọn i ṣe ṣugbọn ti igbesi-ayé wọn yatọ si bẹẹ. Oun ko fẹ ki wọn jẹ eniyan alarojuṣe ṣugbọn boya o wà lọdọ wọn tabi kò si, o fẹ ki igbesi-aye wọn jẹ ẹri si agbara Ihinrere ti i maa pa ni mọ́. Otitọ ni eyi jẹ pe lati ọpọlọpọ iran sẹyin awọn ẹlomiran a maa fi otitọ ọkàn tẹle Ọlọrun niwọn igba ti wọn ba ni aṣiwaju nipa ti ẹmi ti i ṣe alakikanju, ṣugbọn nigba ti awọn aṣiwaju naa ba pa ipo dà, igbagbọ́ wọn a si yẹ̀. Ọlọrun n fẹ ki a duro bi o tilẹ jẹ pe awa nikan ni. Igba miiran le de ni igbesi-ayé wa ti a o jinna réré si iranwọ awọn Onigbagbọ́ ti o jafafa julọ, ṣugbọn a gbọdọ le sọ nipa tiwa pe a duro ṣinṣin ninu igbagbọ́.

Nitori pe Onigbagbọ ki i gbẹsan nigba ti o ba ni idojukọ le dabi iwa ọ̀dẹ̀ loju awọn ọ̀tá Ihinrere. Ṣugbọn lati duro jẹẹ ki a si wo bi Ọlọrun yoo ti jà fun wa, eyi ni iṣẹgun. Paapaa ni akoko idojukọ tabi iyiriwo ki i ṣe tiwa lati gbẹsan bi ko ṣe lati ranti Ọrọ nì ti o wi pe: "Ọlọrun ki yio ha si gbẹsan awọn ayanfẹ rẹ̀, ti nfi ọsán ati oru kigbe pè e, ti o si mu suru fun wọn? Mo wi fun nyin, yio gbẹsan wọn kánkán" (Luku 18:7, 8). A kà a ninu ẹ̀kọ́ yii pe jijẹ iya nitori ti Rẹ̀ jẹ apakan Ihinrere gẹgẹ bi gbigba A gbọ́ ti jẹ́. Paulu mọ ohun ti oun n sọ, nitori pe o ti jẹ iya ohun pupọ paapaa julọ ni igba naa o jẹ onde ni Romu.

### Iṣọkan

Ijagun Onigbagbọ́ jẹ eyi ti a maa n jà ni ọna ti o yatọ patapata si bi eniyan nipa ti ara ti le rò ó si. Ero eniyan nipa ti ara ni pe irẹ̀lẹ̀ kò le bori ogun pupọ. Ninu iṣẹ rirà ati tita ojoojumọ, awọn ti a n ba lò n fẹ ki eniyan maa fi igbẹkẹle eniyan ninu ara ati agbara rẹ̀ hàn. Ipinnu Paulu ki i ṣe lati kọ nipa iṣowo lati ọjọ-de-ọjọ, ṣugbọn ẹkọ ti o ṣe iyebiye ju bẹẹ lọ eyi ti i ṣe gbigbe pọ̀ ni irẹpọ pẹlu iṣọkan Ẹmi. Ẹkọ ti o kọ́ wọn ni a yàn fun ẹkọ wa lonii ti a o si fi diwọn irẹpọ ti ó wà ninu ijọ wa. Bi o tilẹ jẹ pe a wa ninu ewu pe awọn ọlọgbọn ayé yoo rẹ́ wa jẹ, a gbọdọ gbé igbesi-ayé iwa tutu, ododo ati iwa-bi-Ọlọrun ni ayé isisiyii. Ija tabi ogo asán kò ni ayè ninu igbesi-ayé Onigbagbọ́, ṣugbọn oun a maa ka arakunrin rẹ̀ si yiyẹ ju ara oun tikalarẹ lọ. Oun ni lati maa tọju ohun ti i ṣe ti arakunrin rẹ̀, oun ko si gbọdọ maa fi igba gbogbo wá ohun ti i ṣe ti rẹ̀ nikan. Ere ati anfaani arakunrin rẹ̀ ṣe pataki fun un pẹlu.

### Erò Inu Kristi

Kristi ni apẹẹrẹ wa. O fi ohun gbogbo silẹ ni Ọrun kò si ka ipo giga Rẹ̀ kún, O wá lati gbé inu ayé O si kú ki awa ki o le ni iye. Awa naa pẹlu ni lati tẹle ipasẹ Rẹ̀ nipa lilo ohun gbogbo ti a ni fun itẹsiwaju Ihinrere ki awọn eniyan le ri igbala. Ipo wa, anfaani ti a ni fun okiki tabi lati kó ọrọ̀ jọ ni a gbọdọ fi tayọtayọ pati si apakan ki Ọlọrun le lò wa lati dé ọdọ awọn ti o n ṣegbe. Ẹnikẹni ti oungbẹ Ọlọrun ba n gbẹ yoo ri ẹwa Jesu ninu iwa irẹ̀lẹ̀ iranṣẹ Agbelebu yii, Ẹmi Ọlọrun yoo si fa ọkàn rẹ̀ mọra. Ẹnikẹni ti kò ba ronu nipa Ọlọrun ti kò si bikita fun ọkàn rẹ̀ le ka Onigbagbọ́ si ẹni ẹ̀gan ayé, nitori pe bẹẹ naa ni wọn ṣe si awọn Apọsteli. Yala awọn eniyan gba itọni tabi wọn kọ ọ, Ọrọ Ọlọrun ni amọna ati atọkọ̀ Onigbagbọ́ ninu igbesi-ayé rẹ̀ titi lọ si iye ainipẹkun.

### A Gbé Kristi Ga

Ọlọrun ti gbé Ọmọ Rẹ̀ ga O si ti fun Un ni orukọ ti o bori gbogbo orukọ. Wolii Isaiah sọrọ nipa Orukọ iyanu naa nigba ti o wi pe: "Nitori a bi ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa: ijọba yio si wà li ejika rẹ̀: a o si ma pe orukọ rẹ̀ ni Iyanu, Oludamọ̀ran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye, Ọmọ-Alade Alafia" (Isaiah 9:6). Gbogbo orukọ ti a le fi pe Ọlọrun ni a le fi pe Jesu Ọmọ Rẹ̀. O wà pẹlu Baba nigba didá ayé a si kà pe: "Nipasẹ̀ rẹ̀ li a ti da ohun gbogbo; lẹhin rẹ̀ a ko si da ohun kan ninu ohun ti a da" (Johannu 1:3).

Ni ọjọ kan gbogbo eekun ni yoo wolẹ fun Jesu. Awọn ti wọn wolẹ fun Un nisisiyii ti Oun si gbà wọn ti O di Olugbala wọn ni wọn ri igbala Rẹ̀. Ṣugbọn akoko n bọ̀ ti awọn ti o kọ Ọ yoo wolẹ fun Un fun ogo Ọlọrun ṣugbọn akoko naa yoo jẹ́ igba ti gbogbo ireti igbala ti kọja. Bibu ọlá fun Ọmọ ati sisin In, jẹ́ bibu ọlá fun Ọlọrun; kikọ̀ lati bu ọlá fun Un si jẹ́ titabuku si Baba pẹlu.

O jẹ́ àṣà ni ibi pupọ lati fi Jesu Ọmọ Ọlọrun si ipo yẹpẹrẹ. Awọn ẹlomiran sẹ pe Oun ki i ṣe Ọlọrun, ni ṣiṣe bẹẹ wọn fi ireti igbala ayeraye du ara wọn. "Ko si orukọ miran labẹ ọrun ti a fifunni ninu enia, nipa eyiti a le fi gbà wa là" (Iṣe Awọn Apọsteli 4:12). Jesu Kristi ki i ṣe ẹlẹtàn. O fi ara Rẹ̀ hàn gẹgẹ bi ajinde ati iyè. Ireti igbala wa duro lori pe Ọlọrun ni Oun i ṣe ati lori otitọ Ọrọ Ọlọrun. Bi ẹnikẹni ba ṣe iyemeji si eyikeyi ninu otitọ Bibeli laipẹ lọ titi o le sọ igbagbọ́ rẹ̀ ninu

Bibeli nù patapata. Itumọ Bibeli ti a ṣe ni ède Gẹẹsi ni akoko ijọba James (Ọba ilu Gẹẹsi) ni itumọ ti o dara julọ, oun ni a si ni ireti pe o le ṣe amọna wa lati ayé yii lọ si inu Ogo. Awọn eniyan ti wọn ṣe iyemeji pe Jesu jẹ Ọlọrun ni wọn tumọ Bibeli ni ọ̀na miiran ti wọn pè ni Atunyẹwo kikun; a si mọ̀ pe itumọ ti wọn yii kò le tọ́ ẹnikẹni si ọ̀na Ijọba Ọrun, kaka bẹẹ yoo sé ọna mọ ọ laelae ni. Jesu ni Ọna, bi a ba si kuna lati ri I, nibo ni ireti igbala wa wà? Awọn eniyan kan naa ti wọn sẹ́ ibi Jesu lati inu wundia tabi pe Ọlọrun ni I ṣe yoo wolẹ lori eekun wọn ni ọjọ kan wọn o si jẹwọ Rẹ̀, ṣugbọn ọjọ naa yoo ti pẹ́ jù fun igbala wọn. Oni ni ọjọ igbala, nisisiyii ni akoko itẹwọgba.

**Awọn Onigbagbọ́ Gẹgẹ Bi Imọlẹ**

Apọsteli naa wi pe: "Ẹ mã ṣe ohun gbogbo li aisi ikùnsinu ati ijiyan." Eyi yoo fihan pe Onigbagbọ́ ni lati jẹ ẹni ti o n pagiri mu iṣẹ ṣe; o ni lati ṣiṣẹ -- ki i ṣe lati maa dá rukerudo silẹ, bi ko ṣe lati duro gbọnin fun otitọ. Lati parọ́rọ́ tabi lati ṣai jẹ́ ki imọlẹ rẹ̀ mọlẹ lati yẹra fun atako yoo jẹ iwa igbọjẹgẹ ojo. Bi ayika wa ba ti kún fun ẹ̀ṣẹ ati ibajẹ to bẹẹ naa ni imọlẹ ṣe ṣe danindanin to. Bi a ba lè gbọran si gbogbo itọni inu ẹ̀kọ́ yii a o jẹ imọlẹ ti yoo maa mọlẹ ninu okunkun ti o wà ni ayika wa, a o si "jẹ alailẹgàn ati oniwa tutu, ọmọ Ọlọrun, alailabawọn, larin oniwà wíwọ ati alarekereke orilẹ-ede, larin awọn ẹni ti a nri yin bi imọlẹ li aiye." Bi a ba ni lati ti ara wa mọ́ inu ahamọ kan nitori ki ẹ̀ṣẹ inu ayé má baa ta si wa lara, ireti wo ni ayé yoo ni lati ri imọlẹ Ihinrere ninu wa? Dipo eyiini, Jesu ti fi wa si inu aye lati maa ṣowò titi Oun yoo fi pada wá sinu ayé. Oun ti lọ si Ọrun O si fi wa si ihin yii lati maa tàn fun Oun. Nigba ti O wà nihin O fi Ara Rẹ̀ hàn gẹgẹ bi Imọlẹ ayé, ṣugbọn nisisiyii ti Oun wà ni ọwọ́ ọtun Baba awa ni a jẹ́ imọlẹ Rẹ̀ lati maa tàn ninu ayé.

Ọpọlọpọ eniyan ni wọn ti ba ẹri wọn jẹ́ paapaa ti wọn ti sọ ẹmi wọn nù lẹyin ti wọn ti jẹ́ ohun-elo fun Oluwa nigba kan ri. Wọn kò pa ara wọn mọ́ ninu ifẹ Ọlọrun bẹẹni wọn kò si gbọran si Ọrọ Rẹ̀. Wọn kùn, wọn ṣe awawi, wọn jiyan, wọn si ṣe atako ohun ti Oluwa sọ fun wọn lati ṣe. A ni ominira a si ni ipá lati yan ohunkohun ti a ba fẹ ni gbogbo ọjọ ayé wa. Bi a ba yàn lati gbọran si Oluwa lẹnu Oun yoo ṣe wa ni imọlẹ ti yoo maa mọlẹ siwaju ati siwaju titi di ọjọ pipe e ni.

**Awọn Iranṣẹ Ti A Rán**

Bi o tilẹ jẹ pe Paulu wà ninu ide ni Romu, oun kò le jade lọ bẹ awọn Onigbagbọ wọnyii wò, awọn ẹni ti o fẹran tobẹẹ. O rán Timoteu ati Epafroditu. Wọn ti fi yiyẹ ati jijẹ oloootọ wọn hàn. Wọn jẹ́ iranwọ fun Paulu lati ru ẹrù Ihinrere ni ọjọ wọnni. Paapaa ni akoko yii Paulu sọ pe oun kò ni ẹlomiran ti o duro ti oun nitori gbogbo wọn "ni ntọju nkan ti ara wọn, ki iṣe nkan ti iṣe ti Jesu Kristi." Ẹ wo iru ẹrù nla ti o wà ni ejika awọn Onigbagbọ́ lati duro gbọningbọnin ti Oluwa ki wọn si jẹ́ olotitọ! Bi ọmọ-eniyan ba kunà, Ọlọrun kò ni eto miiran. Njẹ ki ẹni ti n ka iwe yii, bi o ba jẹ́ Onigbagbọ́, gba imọran yii si inu ọkàn ki oun ba le maa tàn bi imọlẹ ninu ayé yii. Fun iwọ ti ko i ti i ni igbala, ẹbẹ mi ni pe ki ọ̀rọ Paulu Apọsteli wọnyii le fi oungbẹ kan si inu ọkàn rẹ. "Alabukún-fun li awọn ẹniti ebi npa ati ti ongbẹ ngbẹ sipa ododo: nitori nwọn ó yo" (Matteu 5:6).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ero inu Paulu nigba ti o bá ranti awọn ara Filippi?
2. Ki ni ohun ti o sọ nipa bi iwa wọn ṣe ni lati ri lẹyin ti wọn ti ni iyipada ọkàn?
3. Iru ọkàn wo ni o fẹ́ ki wọn ni?
4. Ki ni ohun ti o sọ pe Kristi ti ṣe fun wọn?
5. Ki ni nnkan ti o sọ nipa titẹriba fun Kristi?
6. Bawo ni wọn ṣe ni lati maa gbé ki wọn to le jẹ́ imọlẹ ninu ayé?
7. Awọn wo ni Paulu pinnu lati rán si wọn?
8. Ki ni ohun ti o sọ nipa pipese awọn oṣiṣẹ fun iṣẹ Ihinrere ni ọjọ wọnni?
9. Ki ni idi ti Epafroditu ti fi ni iwuwo ọkàn to bẹẹ?
10. Iru ọkàn wo ni Timoteu ti fi ba Paulu ṣe iṣẹ Ihinrere?